# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

VOL I. NO. 19. SATURDAY, NOVEMBER 18, 1922. FOURPENCE.

*Editor:*—ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.


## GBOHUN-GBOHUN.

### EYI ÀRA!!!

A gbọ pe ni ọjọ kanna ti Ọgbẹni J. H. DOHERTY w' ọkọ ni Jimọ *(Friday)* ọsẹ ti o kọja ni ọkan ninu awọn akọwe rẹ̀ fi ọwọ m' ori ti o sare lọ ba a ninu ọkọ pe ole ji Igba pọnun ( £200 ) ti Ọgbẹni na fi si itọju on: o si wa awawi pe ẹnikan ti sọ fun on pe jamba kan yio ṣe on ni ọjọ na gãn, "asọtẹlẹ" yi si ṣẹ lotọ. !! A gbọ pe nwọn ti rú akọwe na mu ati pe ẹjọ na ṣi wa ni KOTU awọn "Akẹran" nisisiyi.

### INA GORI ILE FẸJU.

A ba ọrẹ wa JOSE BRUNET kẹdun òfo ti o ṣe e ni ọjọ diẹ sẹhin niti awọn afọnja rẹ̀ ti o gbina lọsangangan nigbati o sa wọn s' õrun ni ita rẹ̀ *King Street*: iro awọn afọnja na mulẹ tobẹ ti o dabi ẹnipe ina na ti jo gbogbo ile adugbo: a ri awọn enia nsa sihin sa sọhun tite a fi gba a.

### OYI GBE MI LA TÈTÈ, OYI FẸNRẸN KUN-FẸN, OYI GBÉ MI DE 'LE MI, OYI FẸNRẸN KUN-FẸN OYI.

A ki Ọgbẹni Lọya KAYODE, aya rẹ̀ (ọmọ Alufa J. S. Fanimokun ti ko si) ati ọmọ wọn "Kabọ" lati Ilu-Ọba pẹlu awọn Alãji ti o de: ninu ọkọ *Appam* ti o gunlẹ sibi loni. Al fia k' ẹ de?

### ORI KÕ MỌ 'BUSUN.

A gbọ ti ọfọ Ọgbẹni HECTOR JOHNSON aburo Ọgbẹni E. A. T. A. JOHNSON ti Ile-owọ nla, ti o dakẹ ni *Saturday* ti o kọja ni Ilu Ọba nibiti a mu u lọ wo fun itọju ailera rẹ̀. A ba awọn ẹbi rẹ̀ daro.

## KILO TI I ŞE?

A dupę iwe kan ti a npe ni "Aşaro-ohun ti a sọ niti ọrọ Ilu *Nigeria*" ti Ọgbẹni wa HERBERT MACAULAY (Kiniun Onibudo) şęşę şe ni lọ̃lọ̃ yi, ni ede Gẽsi, ninu eyiti o fi ọkan jin wa.

Ọgbẹni na ti fun wa lașę lati yi iwe na si ede wa fun anfani awọn ti o nka Yoruba. A gbọ pe lati igbati iwe yi ti di tita lati ọsę ti o kọja, nşe ni enia nya bi Ẽşú lọ ra a nibiti a gbe ntę ę, Ile Dr. Da ROCHA, *4, Tinubu Street*, Eko. Şile kọ̃kan ni.

---

## ẸNI MỌ 'JÀ K' O JADE ÌJÀ RE!

A şe Idanwo fun awọn ti o fę wọ Işę-Ọba ni Gbangan *Grammar School* ati nibomiran, ni *Saturday* ti o kọja: a ro pe "Ifa yio fọ 're" fun wọn.

---

## "GBA WÈRE NG O GBA WÈRE."

Awọn Ẹgbẹ Ọmọ Ile-iwe *Grammar School* şe Ipade Ijiyan kan ni *Thursday* ọsę yi, ni gbangan Ile-iwe na, ni agogo meje ãbọ alę: Ohun ti a sọrọ le lori ni eyi:—

"Awa ha tó ni *Nigeria*, lati ma dá Işę Ijọba şe?"

Ao kọ bi Ipade na ti şe si, sinu Iwe wa ọsę ti o mbọ.

---

## 7. EREDI AŞỌ ẸBI.

[ Ẹ wo ara Iwe yi ninu Iwe Irohin wa ti *August* ti o kọja. E.D. E.A.]

12. Ẹ jẹ ki a bi ara wa lere kini irẹdi tabi itumọ aşọ ẹbi ti a ndasfi şe Ikita tabi Ikije oku—tabi ti a nda lati şe Iyawo tabi oniruru nkan bẹ larin wa. Mo ti şe abẹwo ati iwadi itumọ aşọ ẹbi ti a nda yi pẹlu ọpọlọpọ ọrọ arojinlẹ—asẹhinwa asẹhinbọ, mo ri pe ọpọlọpọ li o wa larin wa, ti ko tilẹ mọ ohun ti o jẹ rara. Aşọ ẹbi jẹ "ami iya s'ọtọ" larin akojọpọ awọn enia nigbati nwọn ba nşe opo iyawo tabi oku ni oniruru ọna ti a ma fi şe opo iyawo tabi okù ni ilẹ wa. Ami na ni pe iye awọn enia ti o ba da iru aşọ kanna wọ tabi ro, jẹ kiki awọn ẹbi kanna, awọn eni pataki ti o jẹ ẹbi totọ ti oku ti o ku tabi ti iyawo ti a nşe na,—nitori nigbati awọn enia ba ri ọkan tabi akopọ awọn ti o nşe opo yi, nwọn a mọ lẹsẹkanna pe, nwọn jẹ ẹbi ẹniti nwọn nşe oku rẹ yi, tabi iyawo rẹ yi—Eyi ni itumọ aşọ ẹbi.

Njẹ ẹ jẹ ki a yẹ ara wa wo, ni ilu Eko yi loni,—O ha nşe kiki ẹbi tabi ara ẹni nkan lo njumọ da aşọ ẹbi pọ fun opo-kopo ti a nşe? Njẹ alabaşe tabi alabawọ aşọ ẹbi ha tun jẹ ki a mọ awọn ojulowo awọn ẹbi kanna mọ bi? Boya iwọ jẹ Hausa, emi jẹ Şẹkiri, awa mejeji ti jo nşe ọrẹ,—ni akojọpọ, Hausa, Şẹkiri, Tapa, Egun, Aganyin, Awori, Ijẹbu, Ọyọ, Ekiti, Ibarapa, Abọh, Calabar, Sobo, Iyagba, Ilajẹ, Benin, (awọn ara Ado,) Ijaw, Igbari, Ijesha, Ado-Ekiti, Ijẹ, tabi oniruuru awọn ara ilu miran ti a ko darukọ ninu iwe yi. Nigbati Hausa ba nşe Oku tabi Iyawo, gbogbo wọn a ko ara wọn jọ, nwọn a ni, ọkan ninu ẹbi wọn nşe oku tabi iyawo, awon ma da aşọ ẹbi,—nipa bẹ, nwọn a lọ k' ọrunbọ gbese ati da aşọ ẹbi fun oku-oloku tabi iyawo-oniyawo ti ko ba wọn tan lọwọ tabi lẹse. Eyi ti ko ri ọna lati jẹ gbese, a sọkun lọ ba iya tabi baba rẹ, tabi aya a sọkun lọ ba ọkọ rẹ pe, awon ọrẹ on fẹ şe ti oku tabi iyawo, nwọn si ni ki awọn da aşọ ẹbi. Bi ọkọ ba jẹ ẹniti ori rẹ pe, ti o si mọ ohun ti on fẹ fi owo şe,—boya o le sọ pe aye fun iru nkan bẹ (Inawo bẹ) koi ti si fun on nisisiyi.—Nitori eyi, obirin a bọ si igboro lati ma ya ojule ọkunrin ki on ba le ri owo lati fi da aşọ ẹbi. O da mi loju şaka pe, ki şe gbogbo ọkunrin ti o ba şe ileri pe on fun iru awọn obirin bẹ lowo, lẹhin ti o ba ba a şe pọ tan li o ma fi owo na fun u,—a si tun lọ si ibomiran—bayi ni yio şe titi, ti o ba jẹ ẹniti Ọlọrun fi ẹwa oju akata ta lọrẹ diẹ—o le ri owo na gba lati ba wọn da aşọ ẹbi na—Ha! Iru igbesi aiye wo ni eyi? Iru aşa bayi ko ha mu ki ọpọlọpọ agbere ki o pọ larin Eko yi loni bi? Ẹ jẹ ki a ye şe atojubọ. Oku ti ki şe ẹbi rẹ ko le pin ogun fun o, ti o ba jẹ igbagbọ tirẹ ni pe oku npada wa ni ijọ keje lati wa pin ogun gẹgẹ bi igbagbọ awọn Keferi. Ẹ ronu,—ki ẹ si pada kuro ninu ọna iparun ti a nlọ l' aiye wa, papa l' ode Eko yi.

## 8. ALAGBATA TI NSỌ 'JA D' ỌWỌN.

13. Owo yi jẹ owo kan ti mo fẹ le sọ pe o ba awa enia dudu Onigbagbọ ti ilu *Nigeria* mu gẹgẹ bi fila ti ma mba ori enia mu,—nitori pe mo şe akiyesi ohun pupọ ni ilu Eko yi ati ni ilu miran ni agbegbe rẹ, pe ohunkohun ti nwọn ba mu wa ba wa ni ilẹ wa, iba a şe ẹsin tabi aşa lati ilu miran (Ilu Ajeji) wa, ti ao ba gba a, a gba a t' ori t' ẹsẹ, tobẹ ti a fi nina 'nşeju awọn ti o mu ẹsin na tabi aşa na wa ba wa lọ.

Nję, ę ję ki a bi ara wa lere pe, melo ni ninu wa ti o nję orukọ gęgę bi iran rę ?—bikoşe orukọ agbawin ję, ti orilę-ede miran ti o yapa si ti ilę wa. Ę şi Bibeli ki ę si ka a lati *Genesis* titi de *Revelation*, o da mi loju gbangba pe Mose (MOSES) ęniti awọn Imale npe ni Anọbi Musa, tabi Jesu ti a npe ni Kristi (ęniti awọn Imale npe ni Anọbi Yisa) ko kọ ęnikęni lękan ri pe ki nwọn ko kọ orukọ orilę-ede wọn silę, nigbati nwọn o ba di Onigbagbọ, tabi pe ę ko gbọdọ fi orukọ ilę nyin şe Isami *(Baptism.)* Bi ę ba fiyesi ę o ri pe onirunru awọn iran ti o wa ninu Bibeli, nję orukọ gęgębi-işędalę ilę wọn. Ę wo awọn Oyinbo Igęsi, nwọn ję orukọ gęgę bi aşa ilę wọn, bę na si ni awọn ara Rome pęlu. Gęgę bi iran awọn enia dudu sa ti pọ, bę na sa ni ti awọn alawọ funfun, ti a tilę fę le sọ pe nwọn npọju wa lọ, sibę, olukuluku iran wọn nję orukọ ni işędalę ilę tabi iran wọn. Ę wo: nipa orukọ ni a fi mọ German yatọ si France, bę na si ni awọn ilu wọnyi :—Greece, Greecians, Italians, Persians, Egypt ans, Spaniads, Portogues, American ati ọpọlọpọ awọn ilu miran ti a ko darukọ wọn si inu iwe yi.

Bę na si ni larin awa enia dudu pęlu, ki nwọn to mu Ęsin Igbagbọ ati Imale wọ ilu wa.

14. Nitotọ a le jęri ara wa pe orukọ na ni awa enia dudu ma nfi mọ orilę-ede wo ni olukuluku ję larin wa, lati igba atijọ tobę, bi iwọ ko tilę mọ oluwa rę, şugbọn nigbati iwọ ba gbo orukọ rę, wa mọ eya ara ilu wo li o nşe. Sa wo, bi a ba durukọ Ijębu ao mọ lęsękana pe Ijębu li a pe, bi a si darukọ Egun, Ijęsha, Ęgba, Aganyin, Popo, Fanti, apa, Hausa, Şękiri, Sobo, Ijaw, Kurumọ, Timni, Mende, Awori, Ọyọ, Ifę, Aguda, Mahin, tabi Idahomi, Ondo, tabi oniruru orilę-ede t'o wa larin awa enia dudu. Şugbọn lati igbati isin Igbagbo ati Imale ti wọ ilę wa, iru orukọ wo li a nję lati, igba yi wa kọ lati bęrę si korira, jıję orukọ ilę wa ti de pęlu tobę ti awọn ęlomiran tilę nro pe o ję alebu fun awọn lati ma ję orukọ gęgębi orilę-ede rę ninu awa enia dudu. John, Daniel, James, Isiaah, Johnson, George, Jeremiah, Ezekiah, Ezekiel, Tom, ęwę tabi larin awọn Imale, Karimu, Alli, Bakare, Yesufu, Abibu, Jinadu, Belo, Sanusi, Lawani, Gbadamọsi, Sakariyawo, Sadiku tabi Musa. Iru orukọ ba wọnyi kọ la gbawin, ti a nru kiri aiye wa. Mo bere, iran enia dudu wo li o nję awọn orukọ, oniruru ti ilę ajeji ti a kọ si inu iwe yi? Ara, Ę ję k' a ronu awọn ara ilu wọnyi ma nfi wa şe ęlęya. Ę ję k' a di ohun ilę wa mu giri. Akoko to fun wa lati mọ ohun ti a nşe gęgę bi orilę-ede ka ye gba agba mọra aşa ti a ko mọ idi rę papa fun ifi aşọ dudu şe ọfọ oku, ikita ati ikije oku Onigbagbọ, ati igbawin orukọ ilę ajeji ję. "Abọ ọrọ l' a nsọ fun ọmọ 'luwabi b' oba de inu rę ad'odidi."

Emi ni tirę, nitotọ,

EMILEYI.

Eko, Ilu Odo Ọya.

## KILOPO? No. 4.

LATI ỌWỌ, *EDITOR* EKO AKETE.

[ A ko gbọdọ da Iwe yi tę lai gba'şę.]

---

### ĘWU AŞEJU.

Laişiyemeji ko si ęniti ko mọ pe aşeju ninu ohunkohun ko dara: ninu ọrọ wa yi, a o sọrọ orişi işę meji ti o dabi ęnipe o ni ęwu aşeju ninu, eyi ni işę *Lawyer* ati işę akọwe *(Clerk)*: ki a kọkọ mu işę *Lawyer*.

---

### (*a*) IŞĘ LAWYER.

Ni iwọn bi ọgbọn ọdun sęhin, a le ka iye awọn *Lawyer* to wa larin wa leni-leji: awọn wọnyi si mu bi abę ninu işę wọn: ọla ti a si nfun işę yi nigbana nmu ki awọn onilù ma kọrin ki i wọn bayi pe,

"Eşu ş' ọmọ 'kunrin,
To fi *Lawyer* nşere:"

Şugbọn lati bi ọdun dię rekọja, ọpọlọpọ enia ninu awọn ara wa lo lọ kọ işę yi ni Ilu Ọba, tobę to dabi ęnipe ko tun si işę to niyi to işę yi mọ, bę ogunlọgọ işę miran li o wa bi işę Onişegun, *Doctor*, işę Awọn 'lę, *Suveyor*, işę Akọ 'le, *Architect*, işę Oko *Agriculture*, ati awọn işę bawọnni ti a le lọ kọ ni Ilu oyinbo, ti a si le gba oye fun bakanna: a ko fi eyi ba ęnikęni wi, şugbọn ohun ti a ntọka si ni pe a npa ara wa lopo, ati ma tọwọ tabi şigbo lọ, "gba *Lawyer*" nilu Oyinbo, boya ki awọn enia le ma wipe "*Lawyer* ni lamọrin;" boya irufę ęni bayi şina lọ kọ işę *Lawyer* ni, nigbati o fi ọna işę rę pāpā ti a ti yan mo ipin rę lati ode ọrun silę; ohun to si nkęhin rę nigba pupọ nipe irufę *Lawyer* yi yio ma fi inu ke "abamọ," nigbati o ba ję pe enia ko dari sọdọ rę girigiri fun işę; irufę ọrọ yi fi itumọ owe yi han, to wipe. "O nbere ibi t' ọja ta, o ko bere lọwọ ori?" bawo ni ibati dara to ti a ba nronu bi iru işę kan ję ọna wa, ka to ma nu ori mọ. Gbogbo wa la mọ pe ọbę ti ko ni iyọ ninu ki şe ıję, şugbọn Mo bere, ta lo le ję ọpọ iyọ l' ọbę.

# EKO AKETE.

Eko, Saturday November, 18, 1922.

## OGUNNA GBÒ NGBÒ, TI' O NDA 'TỌ L' ẸNU IGBIN.

Laiṣiyemeji, ko si ẹniti ko mọ pe ọ̀rọ ṣorõ sọ, nitori eyi ni a fi nmã p' owe pe "Owuyẹ a ṣorõ sọ bi ọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ li o pa ẹnikan lana," nitorina li o ṣe yẹ lọpọlọpọ pe ti ẹnikẹni ba fẹ gb'ẹnu le ọ̀rọ̀ lati sọ, ibãṣe ọ̀rọ̀ ilu tabi ti isin, ki oluwarẹ na ṣakiyesi ohun ti on nsọ, bibẹ̃kọ, yio "f'ẹnu kọ."

Irufẹ aifiyeṣara bayi li o mu ki a ri Iwe titun kan ni ọjọ Jimọ̃ *(Friday)* ọsẹ ti o kọja, ti Ọgbẹni HERBERT MACAULAY (Kinniun Onibudo) ṣẹṣẹ ṣe, ti o si di tità lati ẹnu ọsẹ ti a nwi yi: ninu eyiti a ti ta aimọye rẹ̀ lai jẹ pe ẹnikan tabi Iwe-irohin kan polongo rẹ̀ ṣãju.

Nigbati a ka iwe na finni-finni, ti a si ri itan nlanla ati ọ̀rọ otitọ ti o mbẹ nibẹ̀ ni ikan-ko-jọ-kan, a ke "Sãfulà" pe nitotọ, "Ọba li o to ẹhin erin fun" nitori iwe na fi esì ti o wọ̀ si ọ̀rọ ti Dr. JOHN RANDLE sọ ni Ilu ọba, nipasẹ ọran Ilu *Nigeria*, eyiti a si tẹ̀ sinu Iwe-irohin *West Africa* ti ọjọ keji oṣu *September* ọdun-ni.

Ẹ̀wẹ, iwe Idahun na si fi Aṣiso ọpọlọpọ ti o wa ninu ọ̀rọ Oniṣegun na han, lai tun sọ ti aṣiri nla ti o tu, tobẹ ti ko si ẹniti o le ka iwe na pẹlu ọkan ti kò "gbà-bọ̀di" ti ki yio kan sãra si ẹniti o ṣe e; fun ọ̀rọ̀ agbeka ati gasikiya ti oluwarẹ fi bi eyiti Oniṣegun JOHN RANDLE nã sọ wo.

Boya a le ri ẹnikan ti yio wipe Iwe na ko yẹ ni kikọ, tabi pe ohun ti a ri ka ninu rẹ̀ ko wọ̀: a fẹ̃ ṣe ibẽre kan lọwọ irufẹ ẹni bẹ̃ pe ti ẹnikan ba dide lọ si ilu okẽre, ti oluwarẹ na si di ẹru ti ki i ṣe ti enia kan ti o wa ni ilu ru u, ti ẹniti a wipe o lọ si ilu okẽre yi si fẹ gba ẹni bayi lu Ijọba nipa ọ̀rọ̀ ti o sọ fun awọn sanmanri ilu okẽre na, ti irufẹ ọ̀ro yi si wa di mimọ̀ fun ẹniti o wa ni ile yẹn, ti ko mọ 'kan, titi o fi ri iwe irohin ti a sọ irufẹ ọ̀ro manamana bẹ̃ si ka, ti o si di mimọ̀ fun gbogbo agbaiye: irufẹ ẹniti a purọ mọ bayi ha le dakẹ ki o ma a wo bi "ori-ẹran" lalai ta putu lati ja 'rọ na bi? owe oyinbo kan ko ha kọ̀ iru idakẹ bayi, nigbati a p' owe na pe *The word Silence, means Consent*, eyini ni pe ẹniti a ba ni o ṣe nkan kan, ti ko ba si f' ọhun, njẹ lotọ ni oluwarẹ ṣe e. Njẹ ti a ba ri ẹniti o le dakẹ bayi, oniyẹn le fi ọwọ bo oju ku, tabi ki a ti oju oluwarẹ yan a m' ẹbo !!!

Nitori idi eyi ni iwe ti Ọgbẹni wa na ko "wọ to gbajẹ:" inu wa si dun lati ri i pe awọn ara ilu mọ̀ riri ọrọ Otitọ, nitori ayọ nla ti a ri ti olukuluku fi nka iwe na "Bi õgun ẹni ba da ni loju, a fi gba 'ri" a si ri i pe eyiyi ni Kinniun Onibudo ṣe lati fi ku eru-eke le ori awọn oni "mùtumùtẹ:" o si njẹ iyalẹnu wa pe awọn ẹlomiran wa ti nwọn jẹ adiẹ funfun ko mọ 'ra rẹ̀ lagba, nipa sisọ ọ̀rọ̀ ti oju wọn kọ to Ala-yọnu-sọ, ti ẹ ti jẹ?

A dupẹ lọwọ Ọgbẹni HERBERT MACAULAY fun WURA ti o tà fun gbogbo aiye yi, nipa kikọ iwe iyebiye yi, a si ntọrọ ara lile ati ẹmi gigun fun u, ki o ba le tubọ "tọ wa gbọnju" nipa iṣẹ rere Ilu ti o nfi tayọtayọ ṣe, lai ni ireti ère kan lati ibikibi wa.

GUNNUGUN KI I KU L' EWE !!!

---

### THE HOUSE OF DOCEMO.

LETTERS TO THE EDITOR.

Dear Mr. Editor,

A meeting was held somewhere to obtain Signatures to a letter against Prince Eleko one day last week.

The meeting broke up without success, but the letter reached His Honour The Lieutenant Governor with the annoynmous Signature "B' OMODE O KU.".

Several annoynmous letters have been distributed within the last fortnight through the Post the White-Cap Chiefs, The House of Kosoko, and elsewhere.

I hope shortly to give to the Public a staggering panorama of the "Bed of Intrigues."

H. MACAULAY, C.E.

Kirsten Hall,
Lagos, November 14, 1922.

## *Oran Ilu Nigeria No. 1.*

Aṣaro ti Ọgbẹni HERBERT MACAULAY OLOYE C.E. ṣe lori ọrọ ti DR. JOHN RANDLE OLOYE M.B.,C.M. sọ ni Ilu oyinbo ti a si tẹ si Iwẹ-Irohin ti a npe ni West Africa ti ọjọ keji Oṣu September, 1922.

Enia to ba ṣe "kisa" fun awọn Ọgba rẹ.
Ṣe "kisa" fun Ilu rẹ pẹlu.

Pipọn sapakan wa ninu ọran ilu gẹgẹ bi o ti wa ninu ọran isin gbogbo wa lo si ti mọ ọ lara lati ma gba ọrọ ti awọn ti a fi ṣ' agba ba sọ nitori ipo ẹyẹ ti a fi wọn si, ṣugbọn ti a ba jẹ bẹ iru ọrọ bẹ wo, ao ri pe "ofo ijọkeji ọja" ni.

Ọpọlọpọ enia ni ohun ti a ti fi kọ wọn ni kekere nmu ṣiṣe nwọn a si ma ka ohun wọnni si, eyiti awọn obi wọn ti fi kọ wọn. Bi titobi enia ba ti to, bẹ si ni o yẹ ki a maṣe, jẹ ki ọrọ ti nwọn nsọ nigbamiran ti ko tọ "suna" mu wa ṣina.

Nitorina o jẹ iṣẹ ẹnikẹni ni ilu ti o ja fafa ninu iwe ati ọgbọn lati ke tantan nigbati irufẹ enia ti a ti nwi yi ba "ṣi tẹ" ki awọn ara ilu bi on papa, tabi Ijọba ma ba "fi ori ja 'gbo," Irufẹ nkan bẹ ni eyi.

Dr. JOHN RANDLE, OLOYE M.B. ti Ile Ẹkọ-Ẹgbogi ti Ilu Oyinbo ti a npe ni *Edinburgh*, ti o jẹ enia dudu, ẹniti a bi ni ibi oke kan ti a npe ni "Sugar Loaf" (Irisi oke na dabi irisi iyọ-didun :) ni ileto kekere kan ni Regent o jinna to ibusọ marun si Olu ilu Saro ti a npe ni Freetown ti awọn obi rẹ jẹ akuṣẹ, ẹniti o lọ fun isinmi, niwọn oṣu diẹ, ni Ilu oyinbo, ẹni yi lo lọ si ibi iṣẹ iwe-irohin *West Africa* yi ni adugbo ti a npe ni Fleet Street, *in London*, iwe yi jẹ iwe ti gbogbo agbaiye nka lọsọsẹ, Onişegun yi si sọ ohun to ri si ọran ilu Nigeria, ti a si tẹ sinu iwe-irohin na, ti ọjọ keji oṣu *September* ọdunni, lai jẹ pe Oniwe-irohin na fi ti rẹ kun u.

Ti a bi wipe Onişegun yi tẹ gbogbo ọrọ to sọ baṣubaṣu njẹ ko mura ati ri ẹrẹkẹ rẹ lai gbe jigi : ṣugbọn niti emi eyini ko kan mi.

Awọn ọrọ diẹ wa ninu ọrọ to sọ ti esi tọ si : a ko si mọ idi rẹ to fi lo ọgbọn alumọkọrọyi ni sisọ ọrọ to "bẹtẹ" lu oye to ni bayi.

Ẹnikẹni ti o wu ti o daba ati ma ṣe iṣẹ-ilu, ni lati ni ọpọlọpọ suru nitori nkan miran le wa ti yio mu binu rekọja ala. Ki a ma daṭẹnu le iwa rẹ bi bale ile, Ọgbeni Onişegun JOHN RANDLE, dabi ọkan ninu awọn Olohun-agogo ti nwọn ni nwọn nsọrọ ilu, ti o jẹ pe ti nwọn ba nri pe nwọn nsọ ọtọbọ, lojiji nwọn a si bẹrẹ si "mu koko" nwọn ki i si ni "arafi" kan, lati so ọwọ pọ pẹlu awọn ẹlẹgbẹ wọn lati ṣe ohun to jọ ju kan.

## ỌRAN DIDA-WA-GEDE.

Nipa ọrọ dida-wa-gede ni Iwọ Orun *Africa*, Onişegun yi sọ pe isọkusọ ni ọrọ yi nitoripe kole ṣe ṣe : ti a ba fi ọkan gbe igba ti o ti nşişẹ Egbogi lọna ti Oyinbo nibi lati ọdun 1888, lakọkọ, a fi ṣe igbakeji Onişegnn Ijọba, nigbẹhin-gbẹhin, o nşişẹ larin enia dudu, ati Oyinbo lọpọlọpọ, boya gẹgẹ bi ọna yi ti jin, ati bi o ti jẹpe o mọ igbesi awọn "alaisan" rẹ, o yẹ ki Onişegun na mọ ohun to nsọ nipa irufẹ ọrọ bẹ.

## ILANA TITUN.

Nipa ti ilana titun fun Nigeria, ti SIR HUGH CLIFFORD, sọ ti o si ṣe eto rẹ ni ijọ kọkandilọgbọn oṣu *March* 1922, Dr. Randle sọ bayi pe:—

"Lati ọdun m'ọdun ni awa ti nbẹbẹ fun pe ki Ijọba wa ni *West Africa* jẹ eyiti ara ilu yi o ma yan aṣoju si igbimọ Aṣofin..................Ọjẹgẹ ti a gba lati fi eyi sinu ilana *Nigeria* dun mọ ni ninu pupọ.

Nipa ọrọ ti o jade lẹnu Dr. Randle yi, o da awọn korikosun rẹ silẹ, awọn Wompari *Nigeria*, nwọn ko si ju mejila lọ. O si fi eyi bo otitọ ta si ti on ati awọn ọmọ lẹhin rẹ, gbe si Ẹgbẹ Idapọ ti enia dudu (*National Congress of British West Africa.*) papa ẹka ti *Nigeria* nihin, awọn ti o ti nja ajaku akata pe ki a fi sinu ilana ijọba ti *West Africa* pe ki a ma yan enia si igbimọ aṣofin fun ara wa.

O ye ni ṣakaṣaka nigbati a ba nsọ pe enia jẹ ọta ara rẹ, ṣugbọn ki Dr. Randle dẹ di ọta yanyan si awọn ọrẹ rẹ fihan gbangba pe atako wuruwuru ni ti a ko le fi si ero tabi ki a kọ silẹ lalai fọ 'ru mọ ṣapa.

(*a*) O to ogun ọdun nisisiyi tabi ju bẹ lọ nigbati Ọlọla C. A. Ṣapara-Williams ologbe, Ọgbẹni J. Egerton Shyngle ati ọpọlọpọ awọn ẹlomiran pẹlu Dr. Randle lori aga, ni gbangan Randle ni Broad Street, ti nwọn nş'aṣaro pe ki Eko nikan ma yan enia si igbimọ aṣofin Ijọba, Dr. Randle ko ba awọn to ku sọ kan ki o to ja wọn silẹ lẹburubu ti o lọ gba ipo ti a fi lọ ọ ni igbimọ Ijọba pe ki o wa dipo ọlọla J. J. Thomas ẹniti o gba'ye ati lọ fun isinmi. Oro ijọ ti nwọn o tun ṣe ipade ilu eyiti Dr. Randle jẹ olori aga ni nwọn to ri ka lara iwe ti Ijọba lẹ mọ ode kakiri pe ẹlẹgiri ti j' ọgọnu (*Notice No. 303 in Gazette No. 44, of 1899.*)

(*b*) O to ọdun meji nisisiyi, awọn Ikọmẹsan ninu awọn ẹgbẹ *Congress* lati ilu mẹrẹrin ti nbẹ labẹ Ijọba Gẹsi ni iha iwọ orun *Africa* mu iwe ẹbẹ lọ sọdọ olu Ọba, nwọn si fi han akọwe rẹ agba, ara ohun ti o wa ninu iwe ẹbẹ na niyi :—

"Pe ki a bẹ ọlanla rẹ lati tun ilana ijọba awọn ilu enia dudu ti mbẹ labẹ rẹ ṣe ki a le fi aye fun awọn enia lati yan idaji ninu awọn igbimọ aṣofin

ijọba, ki ẹ si tun da igbimọ nla miran silẹ pẹlu, ti gbogbo awọn ti igbimọ aṣofin yio wa ninu rẹ, ki awọn ara ilu si tun yan enia mẹfa ti yio ma bojuto inawo Ijọba, nwọn osi ma sọrọ fanlala lori inawo ati owo bode ati owo miran ti a ba ngba nwọn o sima fi aṣẹ si ninu rẹ."

(c) Dr. JOHN RANDLE, gẹgẹ bi alaga awọn Obilẹjẹ; fi iwe aramu-kandu sọwọ si olori awọn Ikọ mẹsan ti o wa ni London, ni ijọ ọgbọn oṣu *August*, 1920, pe ko si ẹka *Congress* l' Eko, nwọn fẹ fi eyi ṣe jamba fun Ikọ ti Eko. Ẹniti o kọ ṣaju fi ọwọ si iwe Aramu-kandu yi ni "RANDLE"

Awon Ikọ ti Nigeria ni Ilu Ọba ni, OLOYE OLUWA ti Eko, ati J. EGERTON SHYNGLE, olori awọn Agbẹjọro ti Nigeria, ẹniti o ti wa lẹnu iṣẹ yi bi ati ọdun mejilelọgbọn, tabi mẹtadilọgbọn ninu rẹ lo ṣe l' Eko. Awọn Igbimọ ti Eko eyiti Dr. SAVAGE jẹ Akọwe re, pe ilu jọ si Ẹnu-Ọwa, awọn ti o si jẹ ipe nwọn to ẹgbẹdọgbọn enia, nwọn fi aṣẹ si enia meji ti awọn Igbimọ ti Eko yan, awọn Igbimọ ti Eko pe apejọ yi nigbati nwọn ri iṣẹ buruku ti Dr. RANDLE ati awọn meji miran fẹ ṣe, ọkan ninu awọn ẹniti o kọwe bayi:—

*September* 5. 1920. Awọn ti o fọwọ si waya ṣọwọ si ọ nipa ti si ṣ' oju *Nigeria* ni ipade ti a o ṣe ni London, ni ki nsọ fun ọ pe awọn fẹ Ẹgbẹ *Congress* pupọ, awọn si ngb' ara rẹ ta lọpọlọpọ; ṣugbọn awọn ko fẹ ọna ti a fi yan awọn ti yio ṣe oju *Nigeria* ni ipade na, nitori ẹniti a o ba yan si irn ipade bawọnyi ni lati jẹ enia ti o ṣe giriki. Mo si ni lati tun sọ fun ọ gẹgẹ bi o ti wa ninu waya pe ko si ẹka Ẹgbẹ *Congress* rara l' Eko.

Ninu iwe adamọdi yi, a ko ri otọ kan mu ninu gbogbo rẹ, nitori ni akoko yi gan ni Balẹ ilu Eko kọwe nipa aṣẹ Gomina si Dr. R. A. SAVAGE Akọwe Ẹgbẹ *Congress* l' Eko, pe ki o jẹ ki on mọ itan iṣẹdalẹ Ẹgbẹ yi l' Eko, Akọwe Ẹgbẹ si fi ṣọwọ si i.

## "EMI KO MỌ 'WE."

O jẹ ede ti ọpọ awọn miran ma nfọ nigbati ọran ba di ọran KOTU, ti o di ti *Lawyer*, ti ọran diju pitipiti tan gbã, nigbati Adajọ ba bere pe kini yi ṣe ri bayi? tabi ọran owo yi ṣe ri bayi? awọn miran a wipe "ng ko mọ iwe," omiran a wipe "ng ko mọ iwe kọ, ng mọ ọ kà!" Eṣe? Nigbati agogo *School* nlu ni Ita Tinubu, kini o nwo? Nigbati ti Faji nlu, ti ti Ereko nlu, ti *Breadfruit* nlu, nibo lo wa? Ọmo ti Ọlọrun ha fun ọ nkọ? on na ko mọwe? o ko jẹ ki o kọwe? Ọran di ọran KOTU tan, o nsọ pe o ko mọwe! Ko ṣe pe mo fi iru ẹni bayi ṣe yẹyẹ rara, boya ko ni anfani lati kọ iwe nigba ọmọde rẹ, ṣugbọn ohun to jẹki nta ko iru awọn bẹ ni pe, nigba pupọ ni eke ati manafiki ima nwa labẹ ọrọ won. Tani ki a gbagbọ? Ẹniti o mọ iwe, ti o fun ọ lowo lati fi ṣowo, o ko ma mọ iwe ti o fi nra ọja, tio fi nta a, ti o njere o, o digbati o fẹ rẹ ẹ jẹ, o pe ọ lẹjọ, *Lawyer* mura si ọ, o wa sọ pe o ko mọwe? o ko mọ ohun ti olowo kọ sinu iwe! Ko dara bẹ rara, awawi ti ko lẹsẹ nilẹ ni, afi bo ba jẹ pe olowo fẹ rẹ ọ jẹ li o le kigbe aimọ iwe rẹ. Ṣugbọn ọkan ni, o mọ iwe o, o ko mọ iwe o, *Lawyer* rẹ yi o ṣiṣẹ lasan bi o? Ṣe iwọ na mọ pe "ọran ko ba ojugun lo sọ pe on ko ni ẹran?" "*Lawyer* a ma họ ẹran lara egungun gbigbẹ pẹlu, ṣe iwọ na ni o tilẹ sọ pe ki o wa họ? Bi o ko ba mọ iwe, joko jẹ, maṣe fa ijangbọn rara o.

KONGO.

## Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!

OWO IRANLOWO TI A ṢI RI GBA NI WONYI.

| | £ | s | d |
|---|---|---|---|
| Owo ti a ti ri gba | 9 | 19 | 0 |
| Ọgbẹni O. T. Ṣomẹfun on a/c | 0 | 5 | 3 |
| Aropọ | £10 | 4 | 3 |

Ara ilu, Ẹ jare Ẹ mu jẹ ko rẹ nyin.
A o ma jihin yi lọọọṣẹ, —[ED.—E. A.]

## ORIN BIṢI BI NĀRE.

Anu Adamu ṣe 'ni,
Ẹ o ri aiye kadara ọba Oluwa,
Ohun ta ba ti kunlẹ yan ka to ma bọ
'nu aiye, ko le parun ko ma ṣe,
Enia lo ni riro ọba ni ṣ'ọla,
Epe loja sasi ko, k' a ye d' awo ẹnu kiri,
T' Ọba Oluwa ni yio ṣe.—(*Oro Aye*.)
Ka ma sọrọ ka gbodi Ọlọrun,
Ohun to de, Ọba Oluwa nikan loye.

IYAPỌ.

## PREACHERS FOR TO-MORROW.

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

#### ROMAN CATHOLIC

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ.

| | |
|---|---|
| 6.30—7.30 | 8.30—8.30 |
| 7.30—8.30 | 93.0—10.30. |

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

| | |
|---|---|
| 4.45—5.30 | 6.45—7.30. |

#### ANGLICAN

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | Rev. H. Dallimore |
| 6.30 p.m. | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—St. Paul's (Breadfruit) | Ven Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 9 a.m.—St. John's (Arolọya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9 a.m. & 4 p.m.—St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m.—St. David's (Jordan | Rev. J. A. Leigh |

#### WESLEYAN

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | Rev. J. A. Cole |
| 10.30 a.m.—Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | Bro C. W. F. Shaw |
| 7 p.m. | Rev. D. A. Beckley |

#### AFRICAN (COMMUNION)

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Bro. W. K. Fafunwa |
| 7 p.m. | Bro. Laboye Laleyẹ |
| 9 a.m. & 4 p.m.—Erelu | Rev. Supt. G. A Oke, and J. H. Lawson |
| 9 a.m.—Bethel | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| 6.30 p.m. | Rev. E. A. Akinọla |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Bro. Samuel Ajayi |
| 4.30 p.m. | Bro. L. A Randle |
| 9 a.m.—Ararọmi Church | Bro E. A. Ojo |
| 4 p.m. | Bro Joseph Bandele |

#### EBENEZER

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6.30 p.m. | Bro. M. D. Adegboye |

#### St. STEPHEN'S (EPETEDO.)

| | |
|---|---|
| 9. a.m. | Very Rev. J. G. Campbell |
| 4 p.m. | do. do. |

#### BROTHERHOOD.

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. Arinọla Ibaru |
| 7 p.m. ,, | Pastor. A. Adedeji Isọla |

#### AHMADIA.

| | |
|---|---|
| 5.30 p.m.—Open Air Service (Luther Street.) | Prof. A. R. Nayyar |

#### COLONIAL CHURCH (ODAN)

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

## Scripture Column.

(BY M. BANKỌLE FADIPẸ.)

Nitotọ gẹgẹ bi aya ti fi arekereke lọ kuro lọdọ ọkọ rẹ, bẹni ẹnyin ti huwa arekereke si mi, iwọ ile Israeli. *Jere: 3.20.*

Awa dubulẹ ninu itiju wa, rudurudu wa bo wa mọlẹ, nitori ti awa ti ṣẹ si Oluwa Ọlọrun wa, awa pẹlu awọn baba wa, lati igba ewe wa, titi di oni yi, awa ko gba ohun Oluwa Ọlọrun wa gbọ. *Jere: 3.25.*

Bẹkọ, enia, tani iwọ ti nda Ọlọrun lohun? ohun ti a mọ a ma da ẹniti o mọ ọ lohun pe Eṣe ti iwọ fi mọ mi bayi? *Rom. 9.20*

A! ijinlẹ ọrọ ati ọgbọn ati imọ Ọlọrun! awamaridi idajọ Rẹ tiri, ipa ọna rẹ si ju awari lọ! *Rom. 11.33.*

Njẹ mo wi fun olukuluku enia ti o wa ninu nyin, nipa ore ọfẹ ti a fifun mi, ki o maṣe ro ju bi o ti yẹ ni riro lọ; ṣugbọn ki o le ro ni wọntun wọnsi, bi Ọlọrun ti fi iwọn igbagbọ fun olukuluku.

Nitori onjẹ, maṣe ba iṣẹ Ọlọrun jẹ. *Rom. 14. 20.*

Ki ọwọ Satani ki o maṣe tẹ anfani wa: nitori awa ko ṣe alaimọ arekereke rẹ. *II Kor: 2.11.*

---

## Thanks for Sympathy.

The Rev. J. M. Ologundudu, Mr. J. H. Pelligrim, and Mrs. A. S. Rieff, for themselves and on behalf of the members of their family, both here and at Sapele, take this medium hereby to tender their sincere thanks to all friends, neighbours and acquaintances who by personal calls, presents, letters and telegrams evinced sympathy with them during their recent sad bereavement in the passing-away of their beloved mother—'Mammy Sarah Fatokunbọ. Entered into rest on Monday night, 23rd October, 1922.

---

## CLIMAX.

World's wonder hair beautifier for men only.

Will straighten the most stubborn, coarse, or kinky hair in five minutes, make hair lustre and silky, without the least bit grease, absolutely harmless.

Sophia's cream brown Pomade known as a national hair remedy which feeds, nourishes and beautifies the hair, will eradicate dandruff, grow your hair long, lustrous, soft and fluffy for woman and men; Also assorted kinds of pomade and toilet soap in stock.

DIPO & TUNDE,
P. O. Box 335,
37, Ajiṣomo Street,
Lagos, Nigeria.

---

The public are hereby informed that I have removed from 97, Broad Street to a large premises. Store adjoining 109, Broad Street; where the sale of the "Ajenifuja" Sewing machines best German make will be carried on, also Lady's Hats and Shoes of Elegant and up to date designs and styles. West Africa, News of the world, African 'Messenger and Eko-Akete, can also be had from the store.

VIDAL R. COLE,
Ajenifuja Store,
109, Broad Street, Lagos.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## ARNOLD SCHLESINGER.

### OYINBO JAMANI ONIṢOWO ARA HAMBURG

Ṣi Ile-Owo rẹ si *No. 7*, Ita Labinjọ, l' Eko.

---

Ọgbẹni Oyinbo Jamani yi ti şe "kokari" ati fi awọn ogunlọgọ Irepe-Aṣọ tita rẹ han enia, ni Ile-Owo rẹ ni *No. 7*, Ita Labinjọ, ko jinna si Ita Williams, l' Eko: o ši tun ni Ile-Owo ni Ita Akwaesuk, ni Ilu Calabar.

A pe gbogbo enia ti o ba fẹ ba wa ra ọja lati wa wo oniruru Ọja wa, ati awọn Irepe-Irepe Aṣọ l'orişirişi, tabi Iwe-Aworan Ọja wa. A ti nṣowo lati igba "na-mi nna'lẹ" eyini nị l'ojọ pipẹ lati ọdun *1842*: ina owo wa si ti njo geregere ni Apa-ibi ti o jẹ Ilu Enia Dudu lati iwon ogun ọdun sẹhin titi di oni. A si ni "wabi-wọsi" awọn onibara ti Ọja wa ti dun mọ. Awa nikan l' o nta awọn MASINI IRANSO ti a npe ni "ADLER" ati eyiti a npe ni MUNDLOS (eyi ti a npe ni VICTORIA ri). A si ni MASINI ti awọn Aranbata, ti Aranṣọ ati fun lilo ni 'le. A nta kẹkẹ pupupu (*Motor Bicycle*) ti a npe WANDERER pẹlu ẹrọ-ere sisa rẹ, ati eyiti a npe ni "GOLD COASTER" a si ni *Bicycle* lasan ti a npe ni "COASTER." A ni awọn Egbogi t' o jẹ bi Idan ti a npe ni BULA MATADI ati MOLOKE MONE. A si ni awọn Aworan: oniruru aworan bi ti Oluwa nigbati o wa ni Mọṣalaşi ni Ilu Oyinbo. A si ni Duru ọlọw ati ti ẹlẹsẹ ti o mọ niba fun gbigbe kiri, a si ni Ẹrọ-Olorin (*Gramophone*). A si ni *Cement*, Panu Kikọle, Jigi ti Ferese ati pupọ nkan miran.

A le gba Ekurọ, *Cocoa*, tabi Epo dipo Owo-Ọja ti ẹnikẹni ba ranşẹ lọdọ wa.

Ẹ wawo, Ọja wa pọ to gbajẹ.


---

## IGBẸ L' OWO WA.

### EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

| | | |
|---|---|---|
| Ẹgbẹ Idapọ-Owo (A. & E. T. A.) | £10 10 fun *ton* kan | |
| Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,) | | bakanna |
| Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores) | | do |
| Miller | | do |

### Epo.

£21 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ ọyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

### Cocoa.

Lati £25 de £27 fun *ton* kan bakanna.

---

## "O ṢE 'WỌ NI!" ( FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo oja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

### J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7. Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* ( *Customs Street*, ) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAŞINI-ARANŞỌ ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo 'wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAŞINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, Nwọn si nranşẹ ( *Cement* ) ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AŞIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

---

## Ile Ita 'Egbogi ti Macaulay.

( *Macaulay's Household Dispensary.* )

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla ( *Broad Street*,) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aşẹ ogun pipo ( *Certificated Dispenser* ) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE ỌWO-ỌJA RIRANŞẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

---

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Şẹda, Onini, Owu-Şẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kõtu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

### ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe ( *General Post Office* ) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ ( *Telephone* ) ni 243.

---

## ILE EGBOGI IŞẸ OLODUMARE.

---

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işẹ Olodumare si ọja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orififọ, Inurirun, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.
Iwọ ko tilẹ gbọ orukọ rẹ ndan?
Işẹ Olodunmare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## ALASE LEATHER FACTORY.
"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. LEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams* :—Alawobata, Eko.

---

F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo onișowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ lorișirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JCJO ni oniruru to tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn,
Ni 45, Marina, L'Eko.


---

## "EKO AKETE" je Iwe-Irohin "Ilufemi."

Ko si enia ti o polowo ọja ninu rẹ ti ko b'ode pade. Ede Yoruba ti o jina mbẹ bi Aba. Ẹ re e polowo ọja nyin ninu rẹ. Bi bẹ kọ, Afara nja ọ!

---


AWỌN ẸGBE OYINBO ONIṢOWO TI A NPE NI
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16 18 GERMANY.

Jẹ Awọn onișowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranșẹ ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ ṣibașe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekuro ti a ba fi ranșẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranșẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Kamu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L'Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo onișowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkorin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti ns' oku l' ọrun?
Ki la ti ns' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ, ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


---

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.